<table>
<tr><td colspan="2">UNIVERSITY of MARYLAND CAPITAL REGION HEALTH</td><td>PFS<br>ÌLÀNÀ-IṢẸ́ ÀTI<br>ILANA<br>IWE</td></tr>
<tr><td colspan="2">Àkórí: Owó Ìrànwọ́</td><td>Nọmba Ìlànà:<br>PFS.FIN.01</td></tr>
<tr><td>Aṣẹ̀dá:<br>Àjọ Alamojuto Ìṣúná Aláìsàn</td><td>Ọjọ ti o Bẹ̀rẹ̀ Iṣẹ́:<br>3/2/2017</td><td>Ọjọ Àyẹ̀wo/Àtúnyẹ̀wo:<br>3/2/2017</td></tr>
<tr><td colspan="3">Ẹni ti o fọwọ́ sii:<br>Eileen Pride</td></tr>
<tr><td>A. Alamojuto/Olùṣàkóso</td><td>B. Amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ Olùdari Ẹ̀ka</td><td>C. Olùdarí, Àjọ Alamojuto Ìṣúná Aláìsàn</td></tr>
</table>

## ÌLÀNÀ:

DHS ni ìfarajìn láti pèsè owóìrànwọ́ fún àwọn ènìyàn tí ó nílo ìtọ́jú-ìlera tí wọn kò sì ní èto adójútòfò-ìléra, tàbi tí èto adójútòfò ìléra wọn ko dára tó, tàbí àwọn tí wọn kò kuń ojú òṣùwọ̀n fún èto ìjọba, tàbí tí wọn kò lágbára láti sanwó fún ìtọ́jú pàjáwìrì àti ìtọ́jú tí o pọndandan fún ìléra wọn nítorí bí ìṣúná oníkálukú wọnṣe rí.

iIlànà àjọ DHS ni láti pèsè Owó Ìrànwọ́, èyi dá lórí àìní tàbí owó ìtọ́jú tí ó pọ̀ níye fún àwọn aláìsàn tí ó kún ojú òṣùwọ̀n àwọn àmúyẹ èto ìṣúná, tí irúfẹ́ àwọ́n aláìsàn yìí sì bẹ̀bẹ̀ fún irú ìrànlọ́wọ́ bẹ́ẹ̀. Èróńgbà àwọn ìlàna-Iṣẹ́ tí a kọ sí ìsàlẹ̀ yi ni láti ṣàpéjúwe bí a ṣe le è forúkọsílẹ̀ fún Èto Ìlera,àwọn àmúyẹ fún kíkópa, àti àwọn ìgbésẹ iforúkọsílẹ̀.

Ajọ DHS yóò ṣe àtèjáde àǹfàní fún ètò Owó Ìrànwọ́ lọ́dọọdún nínú ìwé-ìròyìn abẹ́lé, yóò si fi ọ̀rọ̀ àǹfàní tí ó ṣì ṣílẹ̀ yi sí àwọn ojúko tí ó se pàtàki àti ọọfisi ìpolongo. Ìfúnnigbọ́ lóri àwọn ànfàni ni a o fi ránṣẹ́ si àwọn aláìsàn pẹ̀lu iye owó ìtọ́jú wọn. A ó fi àwọn pátákó ìpolongo sí ibí gbóógi tí àwọn aláìsàn má ń gbà kọjá. Ìwé tí ń sọ nípa iye owó ti aláìsan yoo san àti ìwé tí ń ṣàlàyé nípa Ètò Owó Ìrànwọ́ ní a o fún aláìsàn kí a tó dá a sílẹ̀ nílé ìwòsan yoó sì tún wà fún gbogbo aláìsàn tí ó bá bèèrè fun.

A le è fún aláìsàn ni àǹfàní sí Ètò Owó Ìrànwọ́ nígbà tí a bá parí àyẹ̀wò tí a ṣì ṣe àkọsílẹ̀ ipò tí ètò ìṣúna aláìsàn náà wa. Èyí jẹ́ àyẹ̀wò owó-ìtọ́jú tí alaisan jẹ sílẹ̀ ati awon owó tó lẹtọ lati san(pẹ̀lú àwọn àṣùwọ̀n tí o já sí gbèsè àyàfi àwọn àṣùwọ̀n tó wà ní ìgbẹ́jọ́ tí wọ́n sì ti gba ìdájọ́ lori rẹ̀) ati owó-ìtọ́jú ti a sètò lati na. A le è se Ètò Owó Ìrànwọ́ fun aláìsàn ti àpamọ́ wọn bá wà pẹ̀lú àjọ alakójọ kan, èyí sì wà fún àwọn àpamọ́ tí wọn kò tí ì dájọ́ rẹ̀.

Ajọ DHS ní ẹ̀tọ́ nínú èrò rẹ̀ láti mọ̀ bóyá aláìsàn kan ní agbára láti sanwó. Gbogbo àwọn aláìsaǹ tí o bá nílò ìtọ́jú pàjáwìrì ní a ó ṣe ìtọju fún lá ì bìkítà bóyá irúfẹ́ aláìsàn bẹ́ẹ̀ lágbára láti sànwo tàbi kò ní. Fún iṣẹ́ pàjáwìrì/ iṣẹ́ ìkánjú, A ó parí ìforúkọsílẹ̀ fún ètó àyẹ̀wò ìṣúná, a ó gbà á wọ́lé, á ó sì sẹ àyẹ̀wò rẹ, èyí kí yóò ṣe ìdíwọ́ fún aláìsàn láti gba ìtọjú.

## ***PÍPEGEDÉ FUN ÈTÒ NAA***

Ní títẹ̀ra mọ àfojúsún wọn làti pèsè ìtọ́jú tí ó pèye àti láti ṣìpẹ̀ fún àwọn tí kò ní ọ̀nà láti sán owó ìtọ́jú tí ó ṣe pàtàki nipa tí ìlèra wọn, àwọn ilé-iwòsan DHS ń tiraka láti ri wípé ìpò ìṣúná àwọn tí ó nílò ìtọjú kò dènà wọn láti wá tàbí gba ìtọ̀jú.

**Àwọn wọ̀nyí ni àwọn ohun tó le se àkùdé pípegedè fún ètò owó-ìrànwọ́:**

**ÌLÀNÀ, ńtẹ̀síwájú**

1. Àwọn iṣẹ́ tí àwọn oníṣẹ́ ìléra tí kò ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú DHS ń ṣe (fún àpẹrẹ, àwoṅ irinṣẹ́ ìléra tí ó dúróore, iṣẹ́ ìlèra àtojúlé dójúlé)
2. Àwọn aláìsàn tí ìlàna tàbí ètò adójútòfò wọn kò fún wọn ní àǹfàní sí àwọn ètò tí àwọn ilé-iṣẹ́ adójútòfò wọn ń pèse (fún àpẹrẹ, HMO, PPO, Workers Compensation), kò ní aǹfàní sí Eto Owó Ìrànwọ́.
   a. Lápapọ̀, Ètò Owó Ìrànwọ́ kò lè dáhùn fún àwon iṣẹ́ tí ilé-iṣẹ́ adòjùtòfò aláìsàn kọ láti ṣe, bíótilẹ̀wùkíórí, ore-ọ̀fẹ́ lè wà ṣùgbọn èyi da lorí bí ẹ̀jọ ná à bá ṣẹ́ rí nígbà tí a bá ṣe àgbéyẹ̀wò ipa tí ó lè ní lóri ètò ìléra àti àwọn èto míran.
3. Àwọn gbèsè àjẹsílẹ̀ tí ó wáyé nípa àwọn ohun ìpàra tàbí àwọn ohun mírán tí ó ṣe pàtàkì ṣùgbọ́n tí kò ní í ṣe pẹ̀lú ìlera.
4. Àwọn ohun ìmáyédẹrùn aláìsàn.
5. Awọn oúnjẹ aláìsàn àti ibi ìwọsùn.
6. ***Owó-iṣẹ́ àwọn onísègùn tí ó ní í ṣe pẹ̀lú ọjọ́ iṣẹ̀ náà kò sí lára àwọn ètò owó ìrànwọ ti DHS. Àwọn aláìsàn tí ó fẹ́ láti béèrè owó ìrànwọ́ lóri àwọn iṣẹ tí ó jẹ mó ti àwọn oníṣègùn gbọdọ kàn sí oníṣègùn náà tààrà.***

**Aláìsàn lè kùnà láti pegedé fún Etò Owó *Ìrànwọ́* nípa àwọn idí wọ̀nyí:**

1. Kíkọ̀ láti pèsè àwọn ìwé tí a bèrè fún tàbí fífi àlàyé tí kò kún to sílẹ̀.
2. Níní etò adójútòfò nípa HMO, PPO, Workers Compensation, Medicaid, tàbi àwọn ètò adójútòfò míràn tí kó ní àǹfàní sí ile-ìwòsàn nítorí àwọn ìhámọ́/gbèdéke ètò adójútòfò.
3. Ikùnà láti san àwọn owó-àjùmọ̀san èyi tí Ètò Owó Ìrànwọ́ ṣe àlàkalẹ̀ rẹ̀.
4. Kíkùnà láti mà a sàn owó tí a ṣàdéhùn pẹ̀lú àjọ DHS
5. Kíkùnà láti ṣe ètò tí ó yẹ lóri àwọn owó tí a jẹ àjọ DHS tẹ́lẹ̀ rí (pẹ̀lú àwọn aláìsàn tí a rán padà sọ́dọ̀ àwọn àjọ míran lóde látàri àwọn gbèsè tí wọn jẹ tẹ́lẹ̀).
6. Kíkọ àyẹ̀wò fún àwọn ètò ìrànlọ́wọ́ míràn kí á tó forúkọsílẹ̀ fún Ètò Owó Ìrànwọ́.
7. Kíkọ láti tú àṣírí àwọn ọ̀rọ̀ tí ó jẹ mọ́ ẹjọ́ tí ó wa nìle ẹjọ́.
8. Àwọn adarí-ìlú láti ilẹ̀-òkèèrè tí ó wá sí ilẹ́ Amẹrika láti gba ìtọ́jú nípa tí ìṣègùn.

Àwọn aláìsàn tí wọn kò pegedé fún ètò náà yóò ní láti san iye gbèsè wọn tí ó ba wà nílẹ a sì lè fí wọn sun àwọn agbowo-ipá tí wọn ba kọ̀ láti san owó náà láarin akókò tí wọn ṣádéhùn.

Awọn aláìsàn ti wọ́n ṣàfihan pé àwọn kò ní iṣẹ́ lọ́wọ́ tí wọn kò sì ní ètò adójútòfò kankan yoo forúkọsílẹ̀ fún Ètò Owó Ìrànwọ́ àyàfi tí wọ́n bá pedegé fún Ètò Owó-Ìrànwọ ti àwọn Aláìní. Tí aláìṣaṅ náa bá pegedé fún COBRA, Olùdámọ̀ràn ìṣúna/ alakóso yóò ṣàyẹ̀wo èto ìṣúna aláìsàn náà làti san owó ìdójútòfo COBRA, yóò si jábọ̀ àwọn àmọ̀ran rẹ̀ fún àwọn Adarí Àgbà. Ẹni-kọ̀ọ̀kan tí ó bá ní owó láti ra ètò adójútòfò ìlèra ní a ó gbànímọ̀ràn láti ṣe bẹ́ẹ̀, éyí jẹ́ ọ̀nà láti ní àǹfànì tààrà sí àwọn iṣẹ́ ètò ìlèra àti fún ìlèra oníkálùkù.

A o gbé ìṣirò iye owo náà le ọna 200-500% iye owo ti ó ń wọ́le gẹ́gẹ́ bí àtẹ̀jáde Ìlàna ọlọ́dọọdún àjọ adójútìṣẹ́ tí wọn fi sínu àkọsílẹ̀ Ìjọba-àpapọ̀. Àwọn ìlàna tuntun yìí yóò bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ ní oṣù àkọ́kọ́ lẹ́yìn àtẹ̀jadé.

## ***<u>Owó Ìrànwọ́ fún àwọn ẗikò ní Olùrànlọ́wọ́</u>***

A le è ṣe àgbéyẹ̀wò aláìsàn láti mọ̀ bóyá ó pegedé fún Ètò Owó-Ìrànwọ fún àwọn tí kò ní Olùrànlọ́wó. Àwọn ìgbà míràn wa tí o farahàn pe aláìsàn kan pegedé fún ètò owó-ìrànwọ́ ṣùgbọ́n tí kò si fọọmu ìforúkọsílẹ̀ fún Eto Ìrànwọ nínu faili. Àwọn àlàyé tí ó mú yanyan gbọdọ̀ wá láti ọ̀dọ̀ aláìsàn tàbi láti ibòmíràn tí yóò fi àrídájú tí ó tó láti mú aláìsàn náà yẹ fún étò ìrànwọ owó. Tí ó bá ṣẹlẹ̀ pé kò sí àrídájú láti fi hàn pé aláìsàn pegedé fún ètò ìránwọ́ owó, àjọ DHS ní ẹ̀tọ́ láti ló àwọn aṣojú míràn tàbi àlàyé lati mọ iye owó tí ó wọlé kí wọn le mọ bóya aláìsàn náà pegedé fún Owó Ìrànwọ́ náà àti díndín ìtọ́jú kù èyí ti kó lè ṣàlaìmawáyé. Lógán tí a bá ti mọ̀ ọ́, nítorí bí àbùdá àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ náà ṣe ri, ìrànlọ́wọ́ owó kan ṣoṣo ti a le yọǹda jẹ èyí tí yóò pa iye owó tí ó wà nínú àpámọ rẹ pátápátá. Pípegedé fún ìrànwó-owó fún àwọn tí kò ní olùrànlọ́wọ́ yoo dúró fún ọjọ́ tí a yàn lati ṣe ìtọ́jú aláìsàn. Pípegedé fún eto awọn tí kò ni olùrànwọ dá

**ÌLÀNÀ, ńtẹ̀síwájú**

lori bí ipò tí ayé oníkálùkù bá wà, eyi lè jẹ́:

a. Ètò Iranlọ́wọ́ Ìsegun Òògùn òyìnbó
b. Ọwọ́jà SLMB
c. Ọwọ́jà PAC
d. Àìnílé
e. Ìrànlọ́wọ Ìṣègun àti àwọn aláìsàn tí Medicaid n ṣe ìtọ́jú, fún àwọn isẹ́ tí ER n pese eyi ti o ọwọ́jà àwọn ètò yi kò dé.
f. Iye-owó ti a na lori iranlọ́wọ̩ Ìpèsè Oògùn
g. Kíkún ojú òṣùwọn fún ètó ìrànwọ míràn tí ìbílẹ̀ tàbí tí abẹ́lẹ́
h. Aláìsàn ti o kú lá ì mọ ìle rẹ.
i. Àwọn aláìṣàn tí ó pinnu láti ní àwọn àmúyẹ gbogbo tí a ṣàgbékalẹ̀ rẹ lábẹ Ètò Ìrànlọ́wọ Ìṣègùn tí Ìpínlẹ̀ nìkan nígbàkanrí.
j. Àwọn tí kìí ṣe ọmọ-onilu ilẹ Amẹrika tí a si kà kun àwọn tí kò tẹle ìlanà.
k. Ìrànlọ́wọ Ìṣègùn fún àwọn aláìsan tí ó pegedé fún Èto Iranlọwọ Iṣegun
l. Àwọn alaisan tí kò ni ìdánimọ̀ ( Àwọn àpamọ́ tí kò ní orúkọ tí a si ti gbìyànjú láti ṣàwári tàbi mọ ẹni náà)
m. Kíkógbawọle, nípa òfin èyi tí ilé-ẹjọ́ pọn ní dandan.

## Àwọn iṣe kan ní pàto tàbi àmúyẹ tí kò múni pegedé fún Èto Owó Ìrànwọ́ fún Àwọn Aláìní níwọ̀nyí:

a. Àwọn ìlànà ti o ṣe é yàn nítòótọ́ (fún àpẹrẹ - Ohun Ipara) kò sí lábẹ́ ìpèsè ètò náá.
b. Àwọn aláìsan tí kò ní ètó adójútòfò ti ìlera ṣùgbọ́n tí a rí ní Ẹ̀ka Ìtọ́jú Pàjáwìrì lábẹ́ àṣẹ Ìtọ́jú Pàjáwìrì kò lè ní ẹ̀tọ̀ sí ètò owó ìrànwọ́ fún àwọn alàìní títí di ìgbà tí owó ètó ìgbaradì Maryland Medicaid bá jẹ́ sísan.

## ***ÀWỌN ÌLÀNÀ***

1. Àwọn kan wà tí a ti pèsè sílẹ̀ tí yóò ṣe agbátẹ̀rù ìforúkọsílẹ̀ fun Owó Ìrànwọ́. Àwọn òṣìṣẹ́ yìí lè jẹ àwọn Olùdámọ̀ràn lórí Ìṣúná, àwọn Alákoso Èto Owó Ìrànwọ́ fún Aláìsàn, àwọn Aṣojú tí ń da Oníbara lóhùn, àtí bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ.
2. Gbogbo akitiyan ni a ó ṣe láti pèsè Owó Ìrànwọ́ kí ó to dí ọjọ́ iṣẹ́. Níbi tí ó bá ṣeéṣe, àwọn òṣìṣẹ́ tí a ti yàn yóò pè tàbí pàdé pẹ̀lú aláìsàn tí ó ba bèèrè fún Owó Ìrànwọ́ lati mọ bóyá wọn ní àwọn àmúyẹ̀ àkọ́ní fún ìrànlọ́wọ́.
   a. Òṣìṣẹ́ yóò pári àyẹ̀wò opegede pẹ̀lú ètó Medicaid fún àwọn aláìsàn tí ó lé sanwó fúnrawọn láti fí ìdí rẹ́ múlẹ̀ bóyá aláìsàn náà lágbára láti sanwo.
   b. Àwọn data àkọ́ní ní a o fí sí orí ẹ̀rọ aṣojú kẹta láti mọ̀ bóyá o pegedé. Láti mú kí èyí ṣeéṣe ẹní-kọ̀ọ̀kan tí ó bá forúkọsílẹ̀ gbọ́dọ̀ pèsè àlàyé lóri owó-àpawọlẹ́ wọn àti bí ẹbí wọn ṣe tóbi tó. Latí ran àwọn tí ó forúkọsílẹ̀ lọ́wọ́ làti pári ètó náà, a ó pèsé ìwé tí yóò jẹ́ kí wọ́n mọ̀ ìrú àwọn ìwé-ẹ̀rí tí wọ nílò láti pèse kí wọn to lè pegedé.
   c. A ó mọ́jútó ìforúkọsílẹ̀ aláìsàn, á ó sí ṣiṣẹ́ lóri ìforúkọsílẹ náà,ẹ̀rọ data aṣojú kẹ́ta pẹ̀lú irinṣẹ workflow yóò tọka si ẹni tó pegedé. Gbogbo aláìsàn tí ó ba bèrè fún Owó Ìrànwọ́ nípa fíforukọsílẹ̀

**ÌLÀNÀ, ńtẹ̀síwájú**

yóò gba lẹta abájáde èsi. Esi bóyá ó pegede tàbi o kò pegedé ní a o pèsè láàrìn ọjọ́-iṣẹ́ mèjì lẹ́yìn ti aláìsàn ba bèrè fún itọ́jú ọ̀fẹ́, ìforúkọsílẹ̀ fún ìrànlọ́wọ́ ìṣègùn, tàbi méjèèjì.

d. Lẹ́yin tí a ba gba ìforúkọsílẹ̀ aláìṣàn, wọn yóò ní ọgbọ̀n (30) ọjọ láti pésè àwọn ìwé tí a nílò làti ṣiṣẹ́ lori ìforukọsílẹ̀ náà kí a tó lè mọ bóyá ó pegedé. Tí a kò bá rí èsì gbà láarin ọgbọ̀n ọjọ́, a o fi lẹta ìjákulẹ̀ ránṣẹ́, èyí yóò jẹ ko di mímọ̀ pé a ti fagilé ìforukọsílẹ̀ náà látàri àìpèṣè àwọn ohun ti a nílo fún ìforúkọsílẹ̀. Aláìsàn le tun ìforúkọsílẹ̀ ètó ṣe, ó sì lè pe ẹjọ́ tuntun tí kò bá tẹ̀lé àkókò tí a là sílẹ̀ ní àkọ́kọ́. Ètò ìforúkọsílẹ̀ fún èto Owó Ìrànwọ́ yóò wá fún ó kéré tàn ọjọ 240 lẹyin tí a ba fi ìwé iye owo-ìtọjú ránṣẹ́ lẹ́yìn tí a dá aláìsàn sílẹ̀.

e. A ó pèsè ìfúnnigbọ́ lóri ìlàna ìtọ́jú ọ̀fẹ́ tí ile-ìwòsàn ní fún ẹnikọ̀ọ̀kan nígbà ti a bá fẹ́ gbà á sí ìlé-ìwosàn tàbi gbá ẹni tí ó nílò ìtọ́jú ní ilé-ìwòṣàn.

3. Ìforúkọsílẹ̀ kan péré ní yóò wa fùn gbogbo eto ìrànwọ DHS. Aláìsàn ní láti pèsè ìforúkọsílẹ̀ fún Ìrànwọ-owo tí ó pé pere nípa ọ̀rọ̀-ẹnu tàbi ní kíkọ sínú ìwé. Ni àfikún, a lè béèrè àwọn wọ̀nyí:

a. Ẹ̀dà Ìwé Owó-orí tí Ìjọba-àpapọ̀ tí a ṣẹ̀ṣẹ̀ gbà ( fún ẹni tí ó ba tí gbèyàwó, ẹ̀dà ìwé owó-orí tí ọkọ tàbí aya); àrídájú pé o kìí pawó wọlé (tí èyí bá kàn ọ), àrídájú ìpawówọlé ti ẹgbẹ́jọda (tí èyí bá kàn ọ). Tí o kò bá ní iṣẹ́, a gbọ́dọ̀ rí ìwé àrídájú pé o kò nísẹ́, bii àtẹ̀jáde lati Ọọfisi àjọ adójútòfò tí ń mójútó ọ̀rọ̀ àìnísẹ́, àtẹ̀jáde láti orísun àtìlẹyìn ìṣúná rẹ lọ́wọ́lọ́wọ́ bayi, ati bẹ̀ẹ̀bẹ̀ẹ̀ lo…

b. Ẹ̀dà ìwé-owó tí ó ṣekù sínú àpamọ́ won (tí wọ́n bá jẹ́ ẹni tó ń ṣiṣẹ́) tàbí ẹ̀rí owó àpawọlé míràn.

c. Ìwé Ìfúnnigbọ́ tí ó ń sọ nípa Ìrànwọ́ Ìṣègùn (tí èyí bá kàn ọ́).

d. Ẹ̀dà ìwé owó-ilé tí wọ́n rà tàbí yágbé (tí èyí bání í ṣe pẹ̀lú wọn), tàbí ìwé-àkosílẹ̀ ilé tí ń wọ́n ní tàbí tí wọ́n ń gbé lọ́wọ́.

A o fi Ìwé ẹ̀bẹ̀ fún àwọn àlàyé tí kò pé ránsẹ́ sí aláìsàn. Níbi tí ó bá yẹ, a lè fi ẹnu se àwọn àlàyé tí a nílò.

4. Aláìsàn le è yẹ fún Owó Ìrànwọ́ yálà nítorí kò ní ètò adójútòfò tó dúróore tàbí kí owó ìtọ́jú rẹ̀ pọ̀ níye. Lọ́gán tí aláìsàn ba ti fi gbogbo àwọn ìwé tí ó yẹ sílẹ̀, Olùdámọ̀rán lórí ọ̀rọ̀ Ìṣúná yóò ṣe àgbéyèwó àti ìtúpalẹ̀ ìforúkosílẹ̀ naa, yoo sì fi ránṣe sí ẹ̀ka tó ń bójútó Ọ̀rọ̀ Ìṣúná àwon Aláìsàn fún ìpinnu tí ó kẹ́yìn lórí ìkójú-òsùwọ̀n aláìsàn naa eyi tí ó dá lórí àwọn Ìlànà àjọ DHS.

a. Tí ìforúkọsílẹ̀ tí aláìsàn se fún Owó Ìrànwọ́ bá pé tí ó sì yẹ, Alákoso Ìṣúná yóò sọ bí aláìsàn naa se kún ojú òṣùwọ̀n tó, yóò si fi ránsẹ́ fún ìtẹ́wọ́gbà elẹ̀ẹ̀kejì àtí eyi tí ó jẹ àṣekágbá.

i) Tí aláìsàn kò bá yẹ fún Owó-Ìrànwọ́, Alákosó Ìṣúná yoo sọ ìpinnu yii fún àwọn olùtọ́jú ní ilé-ìwòsàn ,wọn yoo ṣe ètò fún aláìsàn naa láti gba ìtọ́jú tí ó yẹ tí ó sì wà ní ìkápá ilé-ìwòsàn láti se.

ii) Tí aláìsàn kò bá yẹ fún Owó-Ìrànwọ́, Alákoso Ìṣúná yoo sọ ìpinnu yii fún àwọn olùtọ́jú ní ilé-ìwòsàn, fún ìdí èyí a kò ní se ètò ìtọ́jú èyí tí kìí se pàjáwìrì fún aláìsàn naa.

(1) Ìgbìmọ̀ tí ó ń ṣe àmójútó Ìṣúná leè ṣe àtúnyẹ̀wò Ìpinnu rẹ̀ láti má pèṣè alaisan náà fún ìtọ́jú tí ó wà larowoto ilé-ìwòsàn, tàbí ìtọjú pàjáwìrì àti èyí tí kìí se pàjáwìrì, tí aláìsàn naa bá bèèrè fun.

(2) Àwọn tí ó wà nínú Ìgbìmọ̀ náà ni Amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ Adarí àjọ PFS, Adarí-àgbá fùn àjọ Revenue Cycle, Alábòjútó Ẹ̀ka Risk, ati CFO.

(3) CFO yoo bu ọwọ́ lu iṣẹ ìrànwọ́ tó bá ju $50,000.

5. Ẹ̀ka ìtọ́jú kọ̀ọ̀kan ni anfani lati ṣe àṣayàn àwọn ìlànà kọ̀ọ̀kan, eyi ti ko ni lanfani si owó ìrànwọ́.

6. Lọ́gan tí a bá tẹ́wọ́gbà ẹ̀bẹ̀ aláìsàn fún owó iránwọ́, Owó ìrànwọ́ náà leè ṣiṣẹ́ fún òṣú tí a pinnu, ọdún mẹ́ta àkọ́kọ́ àtí oṣù mẹ́fà lẹ́yin rẹ síwájú sí i. Bíótilẹ̀wùkíórí, kò sí gbédéke kan pàto fún ìgbà tí pípegedé fún Owó-ìrànwọ́ yóò dọpin. Ìgbà ìpegedé kọ̀ọkàn yóò dá lóri bí ọ̀rọ̀ náá bá ṣe rí. Ti a bá ṣe àfikún ìtọ́jú kọjá àkókò ti a gbàṣẹ fún, àwọn aláìsàn gbọ́dọ̀ tún ìforúkọsílẹ̀ ṣe fún ètò náà. Ní àfikún, ẹ̀ka tí ó ń mójútó ètò Ìrànwọ́ Owo gbọ́dọ mọ̀ nígbà tí àyípadà bá dé wọn nkan bíi owó tí aláìsàn ń pawọlé, awọn ohun-ìní, owó-níná tàbí ipò tí ẹbí wà. Gbogbo àwọn iṣẹ́ ìpawówọlé lọ́ná àrà tí a ti là

**ÌLÀNÀ, ńtẹ̀síwájú**

kalẹ lorisirisi ọna bí a ti ṣàlàyé rẹ̀ nísàlẹ̀, la ó fòpin sí lọ́gán tí a bá ti buwọ́ lu ẹ̀bẹ̀ aláìsàn láti jẹ̀ àǹfàní owó-ìrànwọ́, a ó sì san gbogbo owó-àjẹsílẹ̀ aláìsàn.

*Iṣẹ́ Gbígba Owó Padà Lọ́na Àrà (ECAs) ní a ó ṣe lóri àwọn àpamọ́ tí kò ní àrínyànjiyán nínù tàbí àwọn àpamọ́ tí kò ní ètò ìsanwó. Àyàfi làbẹ́ àkósò awọn ìṣẹ̀lẹ̀ ti ó gbẹnután, àwọn ìsẹ yìí yóò wáye ní ó kéré tàn ọjọ 120 lẹ́ỳn ìgbà tí a bá ti fi iye-owo sísan ránṣẹ́, a ó sì fí ìfúnnigbọ́ ránṣẹ́ ní bii ọgbọ̀n ọjọ ṣááju ìgbà tí ìṣẹ ECA yó bẹ̀rẹ̀. Á ó kàn sì aláìsàn tí owó ìrànwọ́ bá wà nílẹ̀ á ò ṣì ṣe àgbéyẹ̀wò kíkún-ojú-òṣùwọn fún àwọn tí kò rọwọ́-họrí saájú kí á tó gbé ìgbésẹ̀ kankan.*

*i) A lè ṣe idádúró-owó fún àwọn aláìsàn yìí tí wọ́n bá gba irú ìdàjọ bẹ̀ẹ̀.*

*ii) Ilé-ẹ́jọ́ lè fi àlè lé àwọn ilé tí wọ́n ń gbé. Ìgbékalẹ̀ yìí kò ní lépa títi ilé tí wọn ń gbé pa ṣùgbọ́n a lè dúró lóri ẹ̀tọ́ wa gẹ́gẹ́ bí ayánilówó tó rẹ́sẹ̀walẹ̀ láti gbẹ́sẹ̀ lé ohun-ìní náà.*

*iii) A lè ṣe àtúnṣí àwọn owó tí ó ṣẹ́kù nínú àpamọ́ tí a tì pa ṣùgbọ́n tí ó farahàn nínu àtòkọ-owóyàá tàbí awọn àṣùwọ̀n tí a yà sọ́tọ̀ fún ìdájọ́/ìdádúró tí aláìsàn bá kàn sí àjọ náà pẹ̀lu èsi iye-owo tó ṣẹ́kù. A nírètí pé aláìsàn yóò san gbogbo gbèsè tó ní nílẹ̀ títí di ìgbà tí àjọ́ naa bá sọ pé kí a pa owó tí ó ṣẹ́kù rẹ́.*

*iv) Iṣẹ́ Gbígba Owó Padà Lọ́na Àrà nílò ìfọwọ́sí Ìgbìmọ̀ Ìṣùná.*

7. Tí a bá rí pe aláìsàn kan kò kún ojú-òṣùwọn,a ó ṣe gbogbo akitiyan lati gba owó-àjọsan, owó-àyọkúrò tàbi ìpín owó tí ó yẹ kó ṣẹ́kù ṣaájú ọjọ́ iṣẹ́ tàbi kí a ṣètò rẹ fún gbígbà ní ọjọ́ iṣẹ́.
8. A o fun aláìsàn tí ó ba ṣe ìforúkọsílẹ̀ lọ́na ẹ̀tọ́ ní lẹta àbájáde-èsí tí ó kẹ́yìn.
9. Ìpinnu láti dá owó padà dá lórí ìgbà tí a bá mọ̀ pé aláìsàn kan kò ní agbára láti sanwo èyí tí a ṣe àfiwé rẹ̀ pẹ̀lú ìgbà tí aláìsan san awọn owó náà. A lè dá owó ti a jẹ àláìsàn pada nitori owo ti o san ,èyí jẹyọ látàrí owó ìrànwọ́ tí aláìśán gbà lori iye-owó rẹ̀ tó sẹ́kù. A o da àwọn owó ti alaisan bá san laarin ìgbà tí ó ní ẹ̀tọ́ sí owo ìrànwọ̀ pada tí iye owó naa bá ju iye ti o yẹ kí alaisan san wọlé lọ pẹ̀lù $5.00 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ.
10. Àwọn alaisan tí ó ní anfani sí itọju ilera miran ( fun àpẹrẹ, ètò adójútòfò ti àkọ́kọ́ àti ìkejì tàbi oníṣẹ́ tí abẹ̀ lọ́wẹ̀, tí a tún mọ̀ sí abala-tí-a-yọ jáde) gbọ́dọ̀ lo gbogbo anfani àjọ wọn tán kí wọn tó le forukọsilẹ fún Ètò Owó Ìrànwọ.

## ***<u>Ìpèníja Owó</u>***

Owó ìtọ́jú tí kò sí labẹ́ ètò adójútòfò ti ẹka DHS ni a ó lò lati mọ̀ bóyá alaisan naa yẹ fun eto owó-ìrànwọ́. Àwọn ìlànà tí ò wà ní ìsàlẹ̀ yii ni a yà ṣọ́tọ̀ gẹ́gẹ́ bi afikun ipinnu lati ni anfani si owó-iránwọ́, tí a mọ̀ sí Ìpèníja Owó. A o fun gbogbo alaisan ti o ba forukọsilẹ fun owó-iranwọ ni ètò Ìpèníja Owó

Ètò Ìrànwọ́ Ìṣègùn fún àwọn tó ní Ìpèníja Owó wà fún àwọn tí kò pegedé fún Etò Owó Ìrànwọ́ labẹ́ àwọn ìlànà àwọn ofin yìí: ṣùgbọ́n fún:

1) Awọn ti gbèsè tí wọn jẹ ní àwọn ibùdo DHS jú ìda mẹẹdọgbọn Owo tí ẹbí náà ń pa wọlé Lọ́dọọdún; èyí tí ṣe okùnfà Ìpèníja Owó àti
2) ẹni tí owó àpawọlè rẹ̀ kún ojú òṣùwọ̀n ìpele ìrànlọ́wó yìí.

Fún àwọn alaisan tí ó pegedé fun Ìtọ́jú Ẹ̀dínwo labẹ́ àkóso Ètò Ìrànwọ́ Owo alakọkọ ati pẹ̀lú labẹ́ ètò Ìrànwọ́ fún àwọn tí ó ní Ìpènija Owó, àjọ DHS yoo fi àṣẹ́ sí ẹ̀dínwó èyí tó dára fún alaisan fún awọn ìtọ́jú tó ṣe pàtàkì fún ẹbí láàrin oṣù méjìlá tí ó ju ìdá mẹẹdọgbọn owó ti ẹbi naa n pa wọlé.

**ÌLÀNÀ, ńtẹ̀síwájú**

Gbèsè Oògùn-Èbó ni a mọ̀ sí owo tí a bù ná fún awọn ìtójú ti o ṣe pàtàkì.

Lọ́gan tí a ba ti fọwọ́ sí ẹ̀bẹ̀ aláìsan fún ètò Ìpèníja Owó, ètò náà yóò bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ ní oṣù àkọ́kọ́ ọjọ tì iṣẹ́ náà bẹ̀rẹ̀, yóò si wáyé fún oṣú mejila bẹ̀rẹ̀ láti ìgbà ti a ti pari àyẹ̀wo iforukọsilẹ naa. A o ṣe àyẹ̀wò fun àwọn alàisan lorí bí ipò ilera wọn bá ṣe ri laarin gbèdeke àkókò ìpegedé gẹ́gẹ́ ìgbà àìsàn wọn ti pẹ tó tabi ìgbà tí wọn bẹ̀rẹ̀ si ni gba ìtọjú. Awọn ẹ̀dínwó Itọju ilera tí ó ṣe pàtàkì yoo wà fún alaisan ati mọ̀lẹ́bí rẹ̀ tó sún mọ-ọn jùlọ tí wọn jọ ń gbe ilé fún ìgbà tí a yàn fún wọn. Ètò yiii kò sí fún àwọn ìlànà èyí tí a yàn tàbí tí ohun-ìkunra. Biotilẹwukiori, alaisan tabi oniduro rẹ̀ gbọ́dọ̀ sọ fun ilé-ìwòsàn pé àwọn pegedé ní àkòkò iforukọsilẹ tabi àkókò ìgbàsílé. Lẹ́yin ìgbà tí àkókò tí a fọwọ́ sí bá tẹnubodò alaisan gbọ́dọ̀ tún iforukọsilẹ ṣe kí ó lè tẹ̀síwájú nínú ètò náà Ni àfikún, àwọn alaisan tí a ti fọwọsi lati jẹ anfani èto iranwọ naa gbọdo sọ fun ile iwosan ti ayipada bá bá owo-apawọle, ohun-ini, tabi ipò ti ìdílé wọn wa láàrin ọgbọn ọjọ ti àyípada naa bá ti wáyé.

Gbogbo òṣùwọ̀n ìpegedé, àìpegedé àti àwọn ìlanà fún èto Owo Iranwọ alakọkọ náà ló wà fún ètò Ìrànwọ Ìpènijà Owó, àyàfi tí a ba sọ pé kò rí bẹ́ẹ̀.

## ***Èbè***

- Àwọn aláìsàn ti a kò tẹ́wọ gba ìforúkọsílẹ̀ wọn ní àǹfàní láti bẹ̀bẹ̀ fún àyípadà ìpinnu náà.
- A le è sọ ọ̀rọ̀ ẹ̀bẹ̀ yii lẹ́nu tàbí kí a kọ ọ́ sínú ìwé.
- A gba àwọn aláìsàn nímọ̀ràn láti fí àwọn àkọsílẹ̀ míràn tí ó lè mú ki á yí ìpinnu náà padà rànṣẹ́.
- A n fí ẹ̀bẹ̀ pamọ́ sí inu data ẹlẹri kẹta àti irinṣẹ workflow. Lẹ́yìn èyí ní ìgbìmọ̀ alaṣẹ tó lagbara ju aṣojú tí ó kọ iforukọsilẹ alakọkọ naa yoo ṣe àgbéyẹ̀wò rẹ̀.
- Ti ipele ẹbẹ akọ̀kọ̀ kò ba yọri si yiyi ipinnu ijakulẹ naa pada, alaisan ni ẹ̀tọ́ láti gbé ọ̀rọ̀ náà tọ ìgbìmọ alaṣẹ́ àgbà fún àfikún àgbẹ́yẹ̀wò.
- Fífẹ ọ̀rọ̀ naa loju le mú kí ó gòkè de ọ̀dọ̀ Ọ̀ga Agba Eto Ìṣuná ẹni tí yoo ṣe ìdájọ tí ó kẹ̀yìn.
- A o fún alaisan ti ó ba bẹ̀bẹ̀ fún àyípada ìpinnu nipa fiforukọsilẹ ni lẹta abajade èsì tí ó gbẹ̀yin

## ***Ìdájọ***

Ti a ba padà ríi pé alaisan kan pegedé fún Owó Ìrànwọ́ lẹyin ìgbà ti a tí gbé ìdájọ́ kalẹ̀ tàbi ìwé gbèsè tí a fí ranṣẹ sí àjọ tí ń mójútó ẹ̀yawó, àjọ DHS yoo gbiyanju lati fí ìdájọ naa silẹ tabi fagilé alaye ẹ̀yáwó naa.

**ÌLÀNÀ, ńtẹ̀síwájú**

| Òṣùwọ̀n abala tí a parẹ́ | 100% | 100% | 70% | 60% | 50% | 25% |
|---|---|---|---|---|---|---|
| **Ìwọn Ẹbí** | **Owó-Àpawọlé** | **Owó-Àpawọlé** | **Owó-Àpawọlé** | **Owó-Àpawọlé** | **Owó-Àpawọlé** | **Owó-Àpawọlé** |
| **1** | $12,060 | $24,120 | $27,135 | $30,150 | $36,180 | $60,300 |
| **2** | $16,240 | $32,480 | $36,540 | $40,600 | $48,720 | $81,200 |
| **3** | $20,420 | $40,840 | $45,945 | $51,050 | $61,260 | $102,100 |
| **4** | $24,600 | $49,200 | $55,350 | $61,500 | $73,800 | $123,000 |
| **5** | $28,780 | $57,560 | $64,755 | $71,950 | $86,340 | $143,900 |
| **6** | $32,960 | $65,920 | $74,160 | $82,400 | $98,880 | $164,800 |
| **7** | $37,140 | $74,280 | $83,565 | $92,850 | $111,420 | $185,700 |
| **8** | $41,320 | $82,640 | $92,970 | $103,300 | $123,960 | $206,600 |
| Fún ìdílé tàbi ẹbí tí ó ní jú èǹìyàn mẹjọ lọ, fi $4,180 kun ẹni-kọọkan tí ó bá darapọ̀ mọ wọn. | | | | | | |
| **Oṣùwọ̀n owó-àpawọlé tabi jù bẹẹ lọ Ìlànà Ètò fún àwọn Aláìní fún 2017** | **100%** | **200%** | **225%** | **250%** | **300%** | **500%** |